# IROHIN YORUBA

Eain oro wa—"IWAJU L'OPA EBITI NRE SI"

VOL. IX NO. 428 MONDAY SEPTEMBER 21 1953 KOBO KAN (1d)


# Action Group Jagun O Segun



ỌBA ỌNI IFẸ

**Ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi ni awọn apapọ Igbimọ Aṣoju ati Igbimọ Oloye Iwọ-Orun Nigeria ṣe ipade pataki kan ni Ile Igbimọ Aṣofin Iwọ-Orun Nigeria, Ibadan.**

**Ninu ipade yi ni awọn Apapọ Igbimọ Aṣofin Ijọba Iwọ-orun Nigeria na pa ẹnu pọ, awọn si yan Ọba Alaiyeluwa Aderẹmi Kini Ọni Ifẹ, Oloye Bọde Thomas, Oloye Arthur Prest ati S. L. Akintọla lati pada lọ si ẹnu iṣẹ Iriju Igbimọ Aṣofin Nigeria eyiti awọn mẹrẹrin binu fi silẹ lori ọrọ Ominira Ile Nigeria pe ki o bọsi i ni 1956.**

Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ, ti iṣe Olori Ẹgbẹ "Action Group" ati Alakoso Ijọba Iwọ-Orun Nigeria, sọ ọrọ iwuri pupọ lori Iwa Akikanju ti awọn Aṣoju mẹrẹrin ti Iwọ-orun Nigeria yi nhu ni apejọ awọn Iriju Igbimọ Aṣofin Nigeria ti a yan wọn si, ki awọn to binu fi iṣẹ iriju na silẹ.

O si tun ṣe alaye si i wipe iwa Akikanju yi ni o mu ki Gomina Nigeria fi mu a ka wọn kun alatako, nitoripe nwọn ko gba ojuboro, nwọn ko beru lati mu ifẹ inu awọn ti o yan wọn wa sinu ajọ Igbimọ na ṣe, nwọn ko si fẹ ojusaju ati ohun-rere iwa imọtara-ẹni-nikan.

Eyi na ni o si mu gbogbo ilu feran won lati fi dandangbọn le e pe Af'ori Af'ọrun awọn launa ni awọn o tun yan lọ si ajọ Iriju Igbimọ na nitoripe nwọn ko ya si ọtun tabi si osi kuro ni ọna ẹtọ ti awọn ti o yan wọn lọ nfẹ ki nwọn ma a lọ lori eto iṣẹlu na.



OLOYE BỌDE THOMAS

## Awon Qba P'ero Po Pelu Action Group

Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi lẹhin ti awọn Ọba ati awọn Oloye pari apejọ Igbimọ Aṣofin Ijọba Iwọ-Orun tan lori yiyan awọn aṣoju pada si ajọ Iriju Igbimọ Aṣofin Nigeria tan ni awọn Ọba ati Ijoye wa ṣe ipade pataki miran lori eto ilu.

Nwọn ṣe ipinnu pataki pe lẹhin ti awọn fi ara bale ye gbogbo eto ipade ti awọn Ikọ oselu wa lọ ṣe ni Londọnu wo tan, awọn fi ara mọ gbogbo eto ti Ikọ Ẹgbẹ "Action Group" ṣe ti awọn ipade na ko fi ara mọ.

Awọn si tun lodi si ipinnu ti Ọgbẹni Oliver Littelton Alamojuto Ilu Amọna Ijọba Gẹẹsi fi ọwọ si pe ki Ilu Eko kuro ni abẹ Ijọba Iwọ-Orun Nigeria, nitorina awọn mu wa si ipinnu pe ti ero na ko ba yipada, ki Ijọba Iwọ-Orun Nigeria ya kuro labẹ apapọ Ijọba Nigeria patapata.

Wo oju ewe kẹrin

## Nwon Si Banki Eje L'Eko

Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu ni yi Ijọba ṣi Banki ẹjẹ ni Ile Iwosan (General Hospital) Eko, awọn ti yio ma a gba ẹjẹ na pamọ ni awọn oṣiṣẹ Ile Iwosan na, awọn ti yio si ma a ṣe itọju awọn ti o ba wa fi ẹjẹ wọn tọrẹ sibẹ ni awọn "Lagos Red Cross."

Ni ọjọ na awọn ti o wa ṣe ibẹwo ibẹ ni Ọlọla Mallam Shettima Kashim (Minister of Social Services), Oloye Dọkita S. L. A. Manuwa, (Inspector General of Medical Services) ati Oloye Dọkita O. B. Alakija (Acting Senior Medical Officer).

Awọn ti o kọkọ fi ẹjẹ wọn tọrẹ si "Banki Ẹjẹ" na ni Ọgbẹni Frank Pepple (Superintendent of Police, Colony Mainland) Ọgbẹni Tepiomilli Kapten (Sergeant) Major 68th Military Hospital, awọn Ọgbẹni James Durowade

Wo oju ewe kẹrin

## Alake Se Ase-apeje F'omo-omo Re

Laipẹ yi ni Ọba Alaiyeluwa Ademọla Keji C. M. G., C. B. E. Alake Abẹokuta ṣe ase-apejẹ kan ni agbala Ọlọfẹ (Summer Garden) Afin rẹ, Ake Abẹokuta fun ayọ ọmọ-ọmọ rẹ Adenẹkan Ademọla LL.B., ti o ti ilu Oyinbo de pẹlu ẹkun rere oye iṣẹ Amofin ti o lọ kọ ti o si yege ninu rẹ.

Afin Ọba Alake na kun akunfaya ni ọjọ na nitoripe lati ọjọ ti Ọba Ademọla Keji ti nṣe ase-apejẹ ni Afin rẹ, enia ko pọ to bẹ ẹ ri, awọn Ọba, awọn Ijoye, awọn Ọlọtọ Ilu ati awọn enia pataki l'enia dudu ati Oyinbo ni o peṣẹ sibẹ.

Ki awọn to bẹrẹ ayẹyẹ na nwọn kọkọ ya foto papọ pẹlu Lọya Adenẹkan Ademọla na, pẹlu ayọ ati idunnu ati ẹrin muse-muse ni Ọba Alake na fi ngmu ọmọ-ọmọ rẹ na yika gbogbo ijoko apejẹ na ki gbogbo wọn le mọ ẹniti on nfori rẹ yọ ayọ na.

Nigbati ase-apejẹ na fẹ pari ni Ọba Alake sọrọ, o ki gbogbo awọn ti o wa si ibi ase-apejẹ na o si dupẹ lọwọ wọn lọpọlọpọ o si gba ọmọ-ọmọ rẹ na ni imọran pe ki o tẹle ipasẹ baba rẹ (Adajọ Agba Adetokunbọ Ademọla) ẹniti iwa ati iṣe rẹ nfun on ni iwu-

Wo oju ewe kẹrin

## Ijoba Tun Ise Iriju Pin

Ọba Ọni Ifẹ, Oloye Bọde Thomas ati Ọgbẹni S. L. Akintọla bẹrẹ iṣẹ Iriju wọn ninu Ajọ Iriju Igbimọ Aṣofin Nigeria ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi. Nwọn pin iṣẹ ti Oloye Arthur Prest silẹ, on na ko ni i pẹ de lati ilu Oyinbo.

Bayi ni a pin iṣẹ Iriju na fun wọn nisisiyi i-

Ọlọla Okoi Arikpo, M. H. R. Minister of Mines and Power,

Ọlọla Mallam Abubakar Balewa O. B. E., M. H. R., Minister of

Wo oju ewe kerin



OLỌLA S. L. AKINTỌLA



OLOYE ARTHUR PREST

Layekaye Yoruba Lo Ni Ilu Eko




